**Àwọn olùdásílẹ̀ ilé iṣẹ́ Patryna Media ṣe àfihàn àwọn ohun ìmúṣeré orí kọ̀mpútà méjì tó dára**

*Àwọn ilé-iṣẹ́ ohun ìmúṣeré tó làmìlaka láti orí ilé-iṣẹ́ Warner Brothers, 343 Industries, ArenaNet, Blizzard, Undead Labs And More darapọ̀ mọ́ studiọ tuntun ti Prytania Media ti Fang & Claw ati Dawon Entertainment*

Nínú ìlú New Orleans, ní ìpínlẹ̀ Louisana ní orílẹ̀ èdè USA — August 16, 2023 — Ọ̀gbẹ́ni Jeff Strain (*tí wọ́n jẹ́ ọ̀kan lára olùdásílẹ̀ àwọn ilé-iṣẹ́ bí i ArenaNet, Undead Labs, Crop Circle Games, Possibility Space, tí wọ́n si tún jẹ́ ọ̀kan lára àwọn olùdásílẹ̀ àti olùdarí Studios, Prytania Media)* àti Annie Delisi Strain *(tí wọn jẹ́ ọ̀kan lára àwọn olùdásílẹ̀ ilé-iṣẹ́ Undead Labs, Crop Circle Games, Possibility Space, tí wọ́n sì tún jẹ́ olùdásílẹ̀ àti olùdarí Prytania Media)* láyọ̀ láti ṣàfihàn ohun ìmúṣeré tó dára.

Ilé-iṣẹ́ **Fang & Claw** jẹ́ ilé-iṣẹ́ tó ń ṣe àwọn ohun imúṣeré mérìírí fún ìwúlò àwọn oníbàárà. Pẹ̀lú owó ìdókòwò $3M láti ọwọ́ àjọ Transcend Fund, ilé-iṣẹ́ náà ní àwọn òṣìṣẹ́ tó jẹ́ àgbà ọ̀jẹ̀ nínú iṣẹ́ ṣíṣe ohùn imúṣeré, àwọn ẹni náà ní wọ̀nyí:

- Jeremy Gaffney, Adarí Studio (tí ó tún jẹ́ ọ̀kan lára àwọn olùdásílẹ̀ Turbine Entertainment, àti adárí-àgbà ní ilé iṣẹ́ Blizzard Entertainment )
- Fleur Marty, Olóòtú Àgbà (olùdarí ètò àgbà ní ilé iṣẹ́ WB Games Montreal)
- Chris Venturini, Adárí-ètò (tí ó jé adárí àwòrándẹ̀mí ní ilé-iṣẹ́ ArenaNet, adarí Gameplay ni ilé iṣẹ́ Undead Labs )
- Horla Dociu, Olùdarí Ọnà Iṣẹ́ (tí ó tún jẹ́ adarí Studio Art ni ilé iṣẹ́ 343 Industries àti Sucker Punch Productions )
- Ben Scott, Olùdarí ẹ̀ka ìmọ̀ ẹ̀rọ ( tí ó tún jé olùdarí ẹ̀ka ìmọ̀ ẹ̀rọ CTO tí ilé iṣẹ́ Undead Labs)

Ilé iṣẹ **Dawon Entertainment** darapọ mọ́ ilé iṣẹ́ Prytania Media gẹ́gẹ́ bíi studio tuntun àkọ́kọ́ tó wà ní ìlú Bangalore lórílẹ̀-èdè India. Ilé iṣẹ́ Dawon tí àgbà ọ̀jẹ̀ nínú iṣẹ́ imúṣeré, Arábìnrin Whitney Beltrán ń darí ń gbìyànjú láti ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ohun imúṣeré tó lè gbé ìṣe àti àṣà, orin àti ẹ̀ka ìmọ̀ ẹ̀rọ orílẹ-èdè India láruge.

Ilé iṣẹ́ Fang & Claw àti Dawon Entertainment darapọ̀ mọ́ ilé iṣẹ́ **Possibility Space** àti ilé iṣẹ́ **Crop Circle Games** tó wà lára àmì tó wà lára àwọn àgbéjáde tí Ilé iṣẹ́ Prytania Media Studios.

**Nípa Prytania Media**

Prytania Media jẹ́ ilé iṣẹ́ aládáni tó ń ṣe agbátẹ̀rù ṣíṣe àgbéjáde àwọn ohun imúṣeré mérìírí tuntun jákèjádò gbogbo àgbáyé. Annie Delisi Strain àti Jeff Strain dá ilé iṣẹ́ náà kalẹ̀ ní ọdún 2021. Wọ́n sì ń gba iye àwọn òṣìṣẹ́ ẹ̀ka aṣẹ̀dá ohun imúṣeré, òwò, àti abéṣinkáwọ́ tó lé ní 150 jákèjádò àgbánlá aayẹ́. Prytania Media tún ń ṣètò ìgbanisíṣẹ́, ẹ̀kọ́ṣẹ́ fún àwọn òṣìṣẹ́ tí ó wà láti àwọn ìdílé atàpátadìde látàrí àwọn àjọ bí àjọ Mosaic Initiative àti ètò Pryta nia Media Scholars.

**Nípa Crop Circle Games**

Crop Circle Game jẹ́ studio Prytania Media tí a gbé kalẹ̀ ni ọdún 2021, ni a fí owó ìdókòwò tí ó tó $23M láti ọwó àjọ Transcend Fund ṣe agbátẹ̀rù rẹ̀. Crop Circle Games ń pèsè àwọn ohun ìmúseré fún àwọn aṣàmúlò káàkiri àgbáyé.

**Nípa Possibility Space**

Possibility Space ti a dálẹ́ ní ọdún 2021 gẹ́gẹ́ bí studio ilé iṣé Prytania Media ni a fí owó ìdókòwò tí ó tó $3M láti ọwó àjọ Transcend Fund ṣe agbátẹ̀rù rẹ̀. Possibility Space ń ṣe ìrànlọ̀wọ́ fún ẹgbẹ́ àwọn aṣẹ̀dá eré jákèjádò agbáyé tí wọ́n fẹ́ràn láti tún àwùjọ ṣe.

Fún ìbéèrè ọlọ́kanòjòkan nípa mídíà:
Elise Favis // Prytania Media
elise@prytania.co